# IDANWÒ IGBAGBỌ́

## Jakọbu 1:1-21; 1 Peteru 1:1-9; 4:12-19.

## ẸKỌ 448 – FUN AGBA

**AKỌSORI: "Ibukún ni fun ọkunrin ti o fi ọkàn rán idanwò: nitori nigbati o ba yeje yio gbà ade ìye, ti Oluwa ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ" (Jakọbu 1:12).**

**I. Pipé Nipasẹ Idanwò**

1. A rán ikini si awọn Ọmọ Israẹli ti a tuka si aarin awọn orilẹ-ède, Jakọbu 1:1; 1 Peteru 1: 1, 2.
2. Suuru nipaṣe idanwo a maa mu wa lọ si pipé ninu Jesu, Jakọbu 1:2-4; 5:11; 1 Peteru 5:10.

**II. Aiduro Ọkàn Oniyemeji**

1. Ọlọrun a maa fi ọgbọ́n fun awọn ti o wá a pẹlu igbagbọ́, Jakọbu 1:5; 3:13.
2. Ẹni ti o n ṣiyemeji dabi igbi omi òkun, Jakọbu 1:6-8.
3. Ihinrere a maa gbé onirẹlẹ ga, a si maa rẹ agberaga silẹ, Jakọbu 1:9-11.

**III. Orişirişi Ọrọ**

1. Ere n duro de awọn ti o duro gẹgẹ bi oloootọ, Jakọbu 1:12; 1 Peteru 1:3-9.
2. A n dán olukuluku wò nigba ti a ba ti ọwọ́ ifẹkufẹ ara rẹ̀ fa a lọ ti a si tàn án jẹ, Jakọbu 1:13-18.
3. Oluwa n fẹ awọn oluṣe Ọrọ naa ki i ṣe awọn olugbọ nikan, Jakọbu 1:19-27.
4. O yẹ ki a maa yọ̀ nigba ti a ba n jiya fun Kristi, 1 Peteru 4:12-14; Matteu 5:11, 12.
5. Idajọ bẹrẹ lati inu ile Ọlọrun, 1 Peteru 4:15-19.

## ALAYE

### Jijiya fun Ihinrere

Jakọbu kọ Episteli yii si awọn ẹya Israẹli mejila ti a fọ́n kaakiri ti a si tuka si aarin awọn Keferi. Ṣugbọn ni ọna ti o gbooro ju eyi lọ, eyi jẹ́ ikini si gbogbo awọn Onigbagbọ́ nibi gbogbo.

"Ẹnyin ará mi, nigbati ẹnyin ba bọ́ sinu onirũru idanwò, ẹ kà gbogbo rẹ̀ si ayọ̀". "Idanwò" nihin yii n tọka si ipọnju, iyiiriwo tabi didan ni wò. A ko lo o nihin yii ni ọna pe ki a tan eniyan jẹ lati dẹṣẹ gẹgẹ bi a ti maa n gba idanwò si.

Ọrọ iyanju ti a n sọ nihin ni pe ki a ka si ayọ̀ gbogbo nigba ti a ba n jiya fun Ihinrere, tabi nigba ti Oluwa ba gba ipọnju laaye lati de ba wa, tabi ti O n mu wa la iyiiriwo ti o ṣoro kọja lati sọ wa di pipé ninu aipe wa lati mu wa wá si pipé ninu Jesu Kristi. Itumọ eyi lọna miiran ni pe, nigba ti iyiiriwo ba de, ki o ye wa pe Ọlọrun gba a laye lati mu wa wá si pipe imọ ipo ti a wa si I ni.

Lati ọjọ iwa ni Ọlọrun ti n ni awọn eniyan ti a danwò. Eyi jẹ́ ọna kan ti Oluwa n gba fi wadii ijolootọ wa si I. Iyiiriwo a maa fi ailera wa hàn, a si maa fi ohun ti ó wà ninu ọkàn wa hàn.

A ko le mọ bi agbára ẹrọ ti to titi di igba ti a ba dán agbara rẹ̀ wò. A ko le mọ iduro eniyan fun iwa titọ titi di igba ti o ba wa ni ipo kan ti o ni lati mu iduro rẹ̀ fun otitọ laaarin gbogbo ogun ọta ti o le mu un ṣe ohun ti ko tọ.

A sọ ọrọ kan pe "Ọlọrun a maa yiiri awọn eniyan wò, ki wọ́n ba le ga ju bẹẹ lọ; Satani a maa dán awọn eniyan wò ki wọn ba le ṣubu".

**Ti a Danwò ninu Iná**

Oluwa wi fun Satani pe, "Iwọ ha kiyesi Jobu iranṣẹ mi, …. ọkunrin ti iṣe olõtọ, ti o si duro ṣinṣin, ẹniti o bèru Ọlọrun, ti o si korira iwa buburu" (Jobu 1:8). Satani wi pe: "Iwọ kò ha ti sọgbà yi i ká, ati yi ile rẹ, ati yi ohun ti o ni ká ni iha gbogbo? Njẹ nawọ rẹ nisisiyi, ki o si fi tọ́ ohun gbogbo ti o ni, bi ki yio si bọhùn li oju rẹ" (Jobu 1:10, 11). Bẹẹ ni a ṣí ọgbà naa kuro. Jobu kò wi pe, "Ki ni ṣe ti gbogbo eyi de ba mi?" O wolẹ o si sin Ọlọrun o wi pe "OLUWA fifunni, OLUWA si gbà lọ, ibukun li orukọ OLUWA" (Jobu 1:21).

Wo o bi inu Oluwa yoo ti dùn to lati ri i pe Jobu di iwa titọ́ rẹ mu sibẹ laaarin iyiiriwo ti o le kikan ju lọ ti o le de ba a! Ogun ti ọta gbe dide si Jobu wa bẹẹ fun igba pipẹ ṣugbọn Jobu di igbagbọ́ rẹ mú; ki iyiiriwo yi to pari, o ni, "On "(Oluwa) mọ̀ ọ̀na ti emi ntọ̀, nigbati o ba dan mi wò, emi o jade bi wura" (Jobu 23:10).

Igbagbọ Jobu ninu Ọlọrun ati iwa titọ rẹ ati ireti rẹ ninu ajinde ti jẹ́ iṣiiri fun awọn Onigbagbọ́ lati igba naa wá, lati di ireti wọn mu ṣinṣin nigba ti wọn ba n la idanwo bi iná kọja.

Gbogbo iyiiriwo ti o le de ba ọmọ Ọlọrun ni Balogun igbala rẹ gbà laaye fun ire rẹ, lati sọ ọ di ọkunrin pipe si i ninu Jesu Kristi.

"Ibukún ni fun ọkunrin ti o fi ọkàn rán idanwò: nitori nigbati o ba yeje, yio gbà ade iye, ti Oluwa ti ṣe ileri fun awọn ti o fẹ ẹ" (Jakọbu 1:12).

**Eyi Ti A Kò Ri**

"Ẹniti ẹnyin fẹ lairi" (1 Peteru 1:8). Ohun ti a mọ̀ ni pe mimọ eniyan funra rẹ ni i maa mu ki a fẹran rẹ. A ko i ti fi oju ti ara wa yii ri Jesu, ṣugbọn a mọ̀ pe o ti wẹ ẹ̀ṣẹ wa nù, O ti gbin ifẹ Rẹ sinu ọkàn wa, O si ti fun wa ni ireti kan pe ọjọ kan a o ri I lojukoju. Nitori eyi ni a ṣe fẹ Ẹ.

Tọmasi kò gbagbọ́ pe Jesu ti jinde kuro ninu oku titi o fi fi oju rẹ ri I. Jesu wi pe, "Nitoriti iwọ ri mi ni iwọ ṣe gbagbọ́: alabukun-fun li awọn ti kò ri, ti nwọn si gbagbọ́" (Johannu 20:29).

**Ọgbọ́n**

"Bi o ba kù ọgbọn fun ẹnikẹni, ki o bère lọwọ Ọlọrun, ẹniti ifi fun gbogbo enia li ọ̀pọlọpọ, ti ki isi iba-ni-wi" (Jakọbu 1:5). A n fẹ ọgbọn ti yoo jẹ ki a ni oye titọ́ nipa Ihinrere to bẹẹ ti a o fi le maa ka a si ayọ̀ gbogbo nigba ti a ba n dán wa wò ti a n yiiri wa wò, ki a le fara da a nitori Jesu.

Bi a ba ka Owe ori kẹta a o ri ọpọlọpọ nibẹ nipa ọgbọn. "Ibukún ni fun ọkunrin na ti o wá ọgbọ́n ri, ati ọkunrin na ti o gbà oye" (Owe 3:13). "Igi iye ni iṣe fun gbogbo awọn ti o di i mu: ibukún si ni fun ẹniti o di i mu ṣinṣin" (Owe 3:18). " Awọn ọlọgbọ́n ni yio jogun ogo" (Owe 3:35).

Nigba ti iṣẹ ṣiṣe akoso orilẹ-ede Israẹli kan Sọlomọni, O beere pe ki Oluwa fun oun ni ọkàn imoye. Eyi wu Oluwa, Oun ko si fun un ni kiki ohun ti o beere nikan ṣugbọn ọpọlọpọ ibukun miiran lẹyin eyi. Jakọbu wi pe Ọlọrun a maa "fun gbogbo enia li ọ̀pọlọpọ, ti ki isi iba-ni-wi".

**Eniyan Oniyemeji**

Bi o ba fẹ ọgbọ́n, beere ni igbagbọ́, ni aiṣiyemeji. Ẹni ti o n ṣiyemeji dabi igbi omi okun, ti a n bi siwa bi sẹyin, á gbagbọ́ nigba kan a si maa ṣiyemeji nigba miiran. "Ki iru enia bẽ máṣe rò pe, on yio ri ohunkohun gbà lọwọ Oluwa".

Nigba pupọ ni o jẹ pe iyemeji a maa bẹrẹ nipa kikuna lati jọwọ ohun kan silẹ ninu ọkàn wa ti Oluwa n fẹ ki a jọwọ rẹ fun Oun. Oogun fun iyemeji wà ni igbagbọ́ bi ti ọmọ kekere. Nigba pupọ ni o jẹ pe awọn otoṣi ati awọn ti ko mọwe maa n ni igbagbọ́ yii, ṣugbọn awọn ọmọwe a maa kuna rẹ. "Nipa gbigbọ ni igbagbọ́ ti iwá, ati gbigbọ nipa ọ̀rọ Ọlọrun" (Romu 10:17).

Awọn Olukọni awọn Ju a maa pe eniyan oniye-meji ni ẹni ti o ni ọkàn meji, ọ̀kan fun ayé ekeji fun Ọrun. Ko fẹ fi ayé silẹ, ko si fẹ jọwọ Ọrun silẹ; sibẹ ọ̀kan ṣoṣo ni o le ni. A gbà wa niyanju lati ni ọkàn kan ti n tẹjumọ ogo Ọlọrun.

**Iyiiriwo ati Idanwò**

Bibeli sọ fun wa gbangba pe iyiiriwo ati idanwò n duro de ọmọ Ọlọrun, ṣugbọn n gbà wá niyanju lati fi ayọ̀ là wọ́n kọja. "Koro ni fun fadaka, ati ileru fun wura: bẹ̀li OLUWA ndan aiya wò" (Owe 17:3). "Gbogbo ibawi kò dabi ohun ayọ̀ nisisiyi, bikoṣe ibanujẹ; ṣugbọn nikẹhin a so eso alafia fun awọn ti a tọ́ nipa rẹ̀, ani eso ododo" (Heberu 12:11).

**Ere Ikẹyin**

Jesu wi pe, " Alabukún-fun li ẹyin, nigbati nwọn ba nkẹgan nyin, ti nwọn ba nṣe inunibini si nyin, ti nwọn ba nfi eke sọ̀rọ buburu gbogbo si nyin nitori emi. Ẹ mã yọ̀ ki ẹnyin ki o si fò fun ayọ̀: nitori ère nyin pọ̀ li ọrun" (Matteu 5:11,12).

Jakọbu ni, "Nigbati ẹnyin ba bọ́ sinu onirũru idanwò, ẹ kà gbogbo rẹ̀ si ayọ". Peteru ni, "Olufẹ, ẹ máṣe ka idanwò iná ti mbẹ larin nyin eyiti o de si nyin lati dan nyin wò bi ẹnipe ohun àjeji li o de ba nyin: ṣugbọn niwọnbi ẹnyin ti jẹ alabapin iya Kristi, ẹ mã yọ̀, ki ẹnyin ki o le yọ̀ ayọ̀ pipọ nigbati a ba fi ogo rẹ̀ hàn" (1 Peteru 4: 12, 13).

Paulu sọ nipa "ipọnju wa ti o fẹrẹ ti iṣe fun iṣẹju kan", pe o n ṣiṣẹ ogo ainipẹkun ti o pọ̀ rekọja fun wa.

Bibeli sọ fun wa pe idanwo igbagbọ́ wa niye lori pupọ ju wura lọ. Wura le ra ile daradara ati ọ̀pọlọpọ ohun itura ayé yii fun ọdun diẹ. Ṣugbọn idanwò igbagbọ́ wa, fun ọdun diẹ, yoo mu wa wá sinu ogún "aidibajẹ, ati ailabawọn, eyi ti ki iṣa" ni Ọrun.

**AWỌN IBEERE**

1. Ki ni ṣe ti a ni lati ka gbogbo rẹ̀ si ayọ̀ nigba ti a ba bọ́ sinu oniruuru idanwò?
2. Bawo ni a ṣe n dán awọn eniyan wò lati dẹṣẹ?
3. Ki ni ṣe ti a ni lati ni ọgbọ́n ninu idanwò?
4. Ki ni itumọ eniyan oniyemeji?
5. A le jẹ́ alaini ninu ohun ini ayé yii ṣugbọn ninu ki ni a le jẹ́ ọlọrọ?
6. Nibo ni Ọlọrun yoo ti bẹ̀rẹ idajọ?
7. Ki ni ṣe ti idanwò igbagbọ́ niyelori ju wura lọ?
8. Ṣe apejuwe ogún wa ni ọjọ ti n bọ̀ ni Ọrun.